ONDO JOURNAL OF ARTS, 2 (1), 2026
Journal homepage: https://ojaafued.com/index.php/ojall
Recieved 20.11.2025, Revised 02.01.2026, Accepted 10.03.2026, Published 30.04.2026
ISSN:1597-104X

# ÌMỌ̀ ÌJÌNLẸ̀-ÈRÒ YORÙBÁ ÀTI ÌBÁYÉMU NÍNÚ ÀṢÀYÀN ORIN YẸ̀KÍNÌ ÀJÀÓ

**EFEMINI, Comfort Olaitan**

## Àṣamọ̀

*Onírúurú kókó-èrò tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò Yorùbá àti ìbáyému ló sodo sínú orin Yẹ̀kínì Àjàó. Ohun tí ó máa ń jẹ́ àfojúsùn onísẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀, pàápàá ewì alohùn ni láti ri pé gbogbo ìmọ̀ èrò wọn bá ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ mu ní gbogbo ọ̀nà. Èyí kò gbẹ́yìn nínú orin Yẹ̀kínì Àjàó tí a fẹ́ gbé yẹ̀wò nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí. Ewì Yorùbá, èyí tí orin jẹ́ ọ̀kan nínú wọn máa ń ní nǹkan pàtó tí ó dá lé lórí. Àfojúsùn iṣẹ́ ìwádìí yìí ni láti ṣe àfihàn ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò Yorùbá tí ó sodo sínú orin Yẹ̀kínì Àjàó. Nínú iṣẹ́ yìí, a ṣe àgbéyẹ̀wò kókó-èrò Yorùbá àti ìbáyému rẹ̀ nínú orin Yẹ̀kínì Àjàó. Tíọ́rì ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀-wo lítíréṣọ̀ ni a fi ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀. Àbájáde iṣẹ́ yìí fi hàn pé àgbékalẹ̀ orin Yẹ̀kínì Àjàó kún fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìmọ̀-ìjìnlẹ̀-èrò Yorùbá èyí tí ó fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé èso àwùjọ ni orin rẹ̀.*

***Kókó-ọ̀rọ̀:*** *Kókó èrò, ìbáyému, ìmọ̀-ìjìnlẹ̀.*

## Abstract

*The songs of Yẹ̀kínì Àjàó are filled with many ideas related to Yoruba philosophy and its relevance to society. Creative artists, especially oral poets, always try to make sure that their ideas connect with what is happening in society. This is also true of Yẹ̀kínì Àjàó's songs, which this research sets out to examine. Yoruba poetry, of which music is a part, is usually built on certain specific*





*foundations. The main goal of this study is to identify and explain the Yoruba philosophical ideas found in Yẹ̀kínì Àjàó's songs. The study looks at Yoruba themes and how relevant they are within his songs. A literary sociological theory (which examines how literature reflects society) was used to analyze the songs. The findings show that Yẹ̀kínì Àjàó's songs are deeply rooted in Yoruba philosophy, and this confirms that his music serves a social purpose, it speaks to and reflects the life of the community.*

**Keywords**: *Themes, Relevance, Philosophy*

## Ìfáárà

Yẹ̀kínì Àjàó gẹ́gẹ́ bí olórin àtinúdá jẹ́ ọmọ bíbí ìlú Ṣakí ní àdúgbò Àsùnnara Ẹnu Ọjà ní Ìjọba Ìbílẹ̀ Ìwọ̀-Oòrùn Ṣakí, Ìpinlẹ̀ Ọ̀yọ́ ní ọjọ́ kẹrìndínlógún oṣù kẹfà ọdún 1932. Orin dàdàkúadà ni Yẹ̀kínì Àjàó ń kọ ṣùgbọ́n ó pe tirẹ̀ ní àpàlà Ọ̀yọ́ torí pé ìlù àpàlà ni ó ń lù sí orin dàdàkúadà rẹ̀.

Yẹ̀kínì Àjàó gẹ́gẹ́ bí olórin àtinúdá gbé àrà ọ̀tọ̀ wọ inú àwọn orin rẹ̀ èyí tí a fẹ́ ṣe àgbéyẹ̀wọ̀ rẹ̀. Tí a bá wo Yẹ̀kínì Àjàó gẹ́gẹ́ bí olórin, a ri pé lára àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìgbésí ayé rẹ̀ ló fi ṣe àtẹ̀gùn di olórin. Irú ẹbí tí ó ti jáde, agbègbè tí ó ti dàgbà, bàbá rẹ̀ olórin ni ní ìlú Sakí. Bàbá rẹ̀ yìí jẹ́ àwòkọ́ṣe fún un nínú iṣẹ́ orin kíkọ. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìlànà dàdàkúadà ni Yẹ̀kínì Àjàó ń gbé orin rẹ̀ gbà, Àpàlà Ọ̀yọ́ ni ó pe orin rẹ̀ nítorí pé ìlù àpàlà ni ó máa ń lù si ṣùgbọ́n èyí sì jẹ́ kí àgbékalẹ̀ orin rẹ̀ fi díẹ̀ yàtọ̀ sí àwọn olórin bí Hárúnà Ìṣọ̀lá àti Àyìnlá Ọmọwúrà tí a mọ̀ mọ́ orin àpàlà gan-an ní àwùjọ Yorùbá. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ orin Yẹ̀kínì Àjàó ni ó máa ń dá lórí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ àti ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó wáyé ní sàkání rẹ̀, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àṣà ilẹ̀ Yorùbá ni ó farahàn nínú àwọn orin rẹ̀. A rí àpẹẹrẹ àṣà kíkọ orin ìdárò nínú àṣà ìsìnkú nínú orin rẹ̀ tí ó pè ní "Mo gbépo lọ́wọ́". Yàtọ̀ sí èyí, púpọ̀ nínú orin rẹ̀ ni ó ń fi èrò Yorùbá hàn nípa àyànmọ́, ikú, ìlo agbára, ìrírí ayé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nínú àwo orin mẹ́wàá tí Yẹ̀kínì Àjàó ṣe, márùn-ún ni a ṣe

àgbéyẹ̀wò nínú bébà yìí pẹ̀lú onírúurú àpẹẹrẹ. Àwọn orin náà ni: *Owó àti Ọmọ, Ọ̀kánkán Sánmọ̀, Ọ̀rọ̀-ń-bọ́rọ̀-bọ̀, Àwọn Olóṣèlú, Iṣẹ́ Àgbẹ̀* àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A ṣe àṣàyàn àwọn àwo orin wọ̀nyí nítorí ìpèdè tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò Yorùbá tí ó kún inú rẹ̀ fọ́fọ́, èyí sì ràn wá lọ́wọ́ láti tan ìmọ́lẹ̀ sí èrò àti ìgbàgbọ́ Yorùbá bí ó ṣe jẹ yọ nínú orin Yẹ̀kínì Àjàó.

**Ìlànà Ìṣèwádìí**

Ìlànà ìṣèwádìí abala méjì ni a lò. Abala àkọ́kọ́ ni a ti ṣe àkójọ orin Yẹ̀kínì tí ó kọ nígbà ayé rẹ̀. Àkọlé àwọn orin náà ni *Owó àti Ọmọ, Ọ̀kánkán Sánmọ̀, Ọ̀rọ̀-ń-bọ́rọ̀-bọ̀, Àwọn Olóṣèlú* àti *Iṣẹ́ Àgbẹ̀*. Àwọn àwo orin yìí ni a ṣàyàn nítorí àwọn ìpèdè tí ó jẹ mọ́ ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò Yorùbá tí ó hànde nínú wọn. Èyí sì ràn wá lọ́wọ́ láti wa ọkọ̀ iṣẹ́ ìwádìí yìí gúnlẹ̀. Abala kejì ni a ti yẹ onírúurú ìwé wò. Lára wọn ni jọ́nà, ìwé àtìgbàdégbà, ìwé àkànṣe iṣẹ́ àti orí ẹ̀rọ ayélujára. A ṣe àdàkọ àwọn àkójọ-èdè-fáyẹ̀wò yìí, a sì fi tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀-wo-lítíréṣọ̀ ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀.

**Tíọ́rì Àmúlò**

Tíọ́rì tí a fi ṣe òdiwọ̀n iṣẹ́ yìí ni tíọ́rì ìfojú ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀-wo-lítíréṣọ̀. Ọmọ orílẹ̀-èdè Faransé tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Hippolyte Taine ni onísẹ́ lámèétọ́ tí ó ṣe agbátẹrù tíọ́rì yìí. Ìwé àpilẹ̀kọ kan tí ó pe àkọlé rẹ̀ ní "History of English Literature" tí ó gbé jáde ní ọdún 1863 ni o ti ṣe àlàkalẹ̀ tíọ́rì yìí kí àwọn ọmọlẹ́yìn rẹ̀ tó tẹpẹlẹ mọ́ lílò rẹ̀ fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀. Ìmọ̀ nípa ènìyàn àwùjọ, ìbáṣepọ̀ láàrin wọn àti ipa tí irú ìbáṣepọ̀ bẹ́ẹ̀ ń kó lórí àwùjọ ni tíọ́rì yìí jẹ mọ́. Àkíyèsí àwọn onímọ̀ lórí bí ipa àwùjọ ṣe ń farahàn nínú iṣẹ́ wọn ló bí tíọ́rì yìí. Tíọ́rì yìí wáyé nítorí pé àwọn lámèétọ́ nípa àwùjọ ń fẹ́ mọ àwọn nǹkan tó ń ṣẹlẹ̀ láwùjọ láìní àríyànjiyàn nínú. Barber (1979:1) fi èrò tirẹ̀ hàn pé "Sociology is a way of trying to understand the society, its structure, how it works, and the focus that bring about changes in it" (Soṣiọ́lọ́jì jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí a fi ní ìmọ̀ nípa àwùjọ, àkójọpọ̀ àwọn ìlànà rẹ̀, ọ̀nà tí ó ń gbàá ṣiṣẹ́, àfojúsùn tó ń mú àwọn àyípadà wọnú àwùjọ bẹ́ẹ̀). Ohun tí onímọ̀ yìí ń tẹnumọ́ ni pé soṣiọ́lọ́jì jẹ́ nǹkan tí a fi ní òye àwùjọ láti mọ bí a ó ṣe gbóríyìn fún ìwà akíkanjú àti bíbu ẹnu àtẹ́ lu ìwà kòbẹ́gbẹ́mu. Àwọn onímọ̀ jẹ́ kí á mọ̀ pé èso àwùjọ ni lítíréṣọ̀. Ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ló jẹ́ kí á mọ àwùjọ ní àwùjọ. Tíọ́rì ìfojú ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ń fi ìbáṣepọ̀ lítíréṣọ̀ àti àwùjọ hàn. Ọ̀pẹ́fèyítìmí (1997:) sọ pé:

> *Èso àwùjọ ni lítíréṣọ̀, àwọn nǹkan tó ń mi àwùjọ ló ń ti akéwì, iṣẹ́ rẹ̀ àti àwọn olùgbọ́ ewì. Nítorí náà a gbọ́dọ̀ kọ́ nípa ohun tí akéwì bá ṣẹ̀dá gẹ́gẹ́ bí èso àwùjọ. Fún ìdí èyí, òfin tó de eégún ló de ẹlẹ́ẹ̀há. Ìgbàgbọ́ wa ni pé lítíréṣọ̀ àti iṣẹ́ ọnà gbogbo ń tẹríba fún òfin tó de àwùjọ ni. Ìyẹn ni pé, ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ lè ṣàlàyé èròjà inú lítíréṣọ̀ àti iṣẹ́ ọnà mìíràn (o.i 42)..*

Nínú àyọlò òkè yìí, ohun tí Ọ̀pẹ́fèyítìmí ń ṣàlàyé rẹ̀ ni pé ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ni ó bí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ, ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ni ó bí èrò ọkàn àwọn afèdèṣọnà.

Ondo Journal of Arts, Faculty of Arts, Adeyemi Federal University of Education, Ondo. Vol. 2. No. 1&2, 2026 | Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀-Èrò Yorùbá àti Ìbáyému Nínú Àṣàyàn Orin Yẹ̀kínì Àjàó

Ọmọ ilẹ̀ Faransé tí ó jẹ́ onímọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò àti láméètọ́ tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Hippolyte Taine (1828-1893) ló ṣẹ̀dá orúkọ fún tíọ́rì ìfojú ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀-wo-lítíréṣọ̀. Tíọ́rì yìí dá lórí ìgbé-ayé ẹ̀dá nínú àwùjọ, ìgbàgbọ́ wọn, iṣẹ́, àṣà, ìhùwàsí àti ìṣesí wọn títí tí ó fi kan èdè tí wọ́n ń sọ lẹ́nu tí ó jẹ́ pàtàkì fún ìgbésí-ayé ẹ̀dá. Ìdí niyìí tí a fi ṣe àmúlò tíọ́rì yìí fún ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò Yorùbá àti ìbáyému nínú orin Yẹ̀kínì Àjàó, torí pé ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ni gbogbo orin rẹ̀ tí a gbé yẹ̀wò dá lé lórí. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀, iṣẹ́ lítíréṣọ̀ kan kò lè tayọ àṣà àwùjọ tí lítíréṣọ̀ náà ti hù jáde. Gbogbo àyọlò inú orin Yẹ̀kínì Àjàó tí a ṣe àmúlò ń ṣe àfihàn ìṣesí, ìhùwàsí, iṣẹ́ àti ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ.

Bí a bá wo Yẹ̀kínì Àjàó gẹ́gẹ́ bí olórin ìbílẹ̀, ó máa ń fi àwùjọ sókàn nínú èrò rẹ̀. Àwọn nǹkan tí ó jẹ mọ́ iwà nípa ọmọnìyàn tó ní í ṣe pẹ̀lú kádàrá, àṣà, ẹ̀sìn, ìṣèlú, àyànmọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ló sodo sínú àwọn orin rẹ̀.

## Èrò Ìjìnlẹ̀ Yorùbá àti Ìbáyému Nínú Orin Yẹ̀kínì Àjàó

Yẹ̀kínì Àjàó jẹ́ ọ̀kọrin tó máa ń gbé èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá jáde nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ orin rẹ̀. Àwọn èrò ìjìnlẹ̀ yìí lè jẹ mọ́ kádàrá, ikú, àríyá ṣíṣe, ìlò agbára àti àwọn mìíràn. Yẹ̀kínì Àjàó gẹ́gẹ́ bí òkọrin ìbílẹ̀ máa ń fi orin rẹ̀ bá àwọn olùgbọ́ rẹ̀ sọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ tí ó ń múni lọ́kàn ró, ó sì máa ń jẹ́ kí àwọn olùgbọ́ rẹ̀ ronú jinlẹ̀ dáadáa. Orin rẹ̀ sì máa ń kọ́ni lẹ́kọ̀ọ́ nípa ìrírí ayé àti bí ènìyàn ṣe lè gbé ìgbé-ayé àlàáfíà àti ìrọ̀rùn. Díẹ̀ lára ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò Yorùbá tí ó jẹyọ nínú orin rẹ̀ nìwọ̀nyí;

## Èrò Yorùbá Nípa Obìnrin

Yẹ̀kínì fi obìnrin hàn gẹ́gẹ́ bí abiyamọ àti ẹni tí ó ní ìfẹ́ ọmọ dé góńgó. Ó fi obìnrin hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú Ọlọ́run. Nínú àwùjọ yòówù ó jẹ́, ọ̀rọ̀ àwọn obìnrin kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nítorí ipa pàtàkì tí wọ́n ń kó nínú àwùjọ. Lára ipa tí wọ́n ń kó ni a ti rí ìmúpọ̀síi ènìyàn nínú àwùjọ. Obìnrin ló ń fi inú ṣoyún, tí wọ́n sì ń bímọ. Àwọn ló ń ṣe tọ́jú ilé, ìtọ́jú ọkọ àti ọmọ. Orísìrísì ìhùwàsí obìnrin, ojú tí àwùjọ fi ń wò wọ́n, ìjẹgẹ̀ba ọkùnrin lórí obìnrin àti onírúurú ohun tí ó lọ̀dìí pọ̀ mọ́ iṣẹ̀dá obìnrin ninú àwùjọ ni ó jẹyọ nínú orin Yẹ̀kínì Àjàó nítorí pé èso ìbágbépọ̀ ẹ̀dá ni orin jẹ́, ipa tí obìnrin sì ń kó nínú ìbágbépọ̀ ẹ̀dá kò kéré. Lára àpẹẹrẹ orin tí Yẹ̀kínì Àjàó kọ nípa obìnrin ni a ti rí àyọ̀lo ìsàlẹ̀ yìí. Ó rí obìnrin gẹ́gẹ́ bí onírera tí nǹkan máa ń rí lára.

> Nǹkan mẹ́ta kan ń bẹ, tóbìnrin ò gbọdọ̀ jẹ
> Obìnrin ò gbọdọ̀ jolú
> Obìnrin ò gbọdọ̀ jawùsá
> Obìnrin ò gbọdọ̀ jẹsin
> Ẹ bi mí, ẹní torí kí ni,
> Torí olú jọ baálé
> Awùsá sì wá fi tútù jọ tọ̀hún
> Iṣín wá fi lílà ẹ tẹ̀le
> A pọ́n lójú a pọ́n lẹ́nu
> Kiní kan wá ń bẹ láàrin rẹ̀ tórórórò

Nínú àyọlò òkè yìí ni a ti rí obìnrin gẹ́gẹ́ bí onírera tí nǹkan máa ń rí lára. Àwọn nǹkan mẹ́ta tí Yẹ̀kínì Àjàó sọ pé obìnrin kò gbọdọ̀ jẹ kì í ṣe èèwọ̀ fún obìnrin. ‘Olú’ tí Yẹ̀kínì Àjàó ní obìnrin kò gbọdọ̀ jẹ kì í ṣe èèwọ̀ fún obìnrin ṣùgbọ́n àwòrán olú fara jọ nǹkan ọmọkùnrin. Torí náà ó ṣe é ṣe kí àwòrán nǹkan ọmọkùnrin máa sọ sí obìnrin lọ́kàn nígbà tí ó bá ń jẹ olú (osun). Awùsá ẹ̀wẹ̀ tí Yẹ̀kínì Àjàó sọ pé obìnrin kò gbọdọ̀ jẹ fara jọ nǹkan rodorodo méjì abẹ́ ọkùnrin (kórópọ̀n). Bákan náà ni iṣin nígbà tí a bá là á fara jọ nǹkan ọmọbìnrin (òbò). Èyí kò bá èrò Yorùbá mu nípa obìnrin torí pé púpọ̀ nínú àwọn obìnrin ló máa

ń jẹ olú, awùsá àti iṣin, ṣùgbọ́n ó ṣe é ṣe kí díẹ̀ nínú wọn tí ó jẹ́ onírera máa ya àwòrán àwọn nǹkan wọ̀nyí sínú ọkàn wọn nígbà tí wọ́n bá ń jẹ ẹ́. Èyí lè fà á kó fi jẹ́ èèwọ̀ fún wọn.

**Obìnrin gẹ́gẹ́ bí Afínjú àti Ológe**

Obìnrin gẹ́gẹ́ bí ìṣẹ̀dá wọn jẹ́ ohun èlò ọlọ́lá àti àrímáleè-mójú kúrò fún ọkùnrin pàápàá tí wọ́n bá múra tán. Gbogbo ẹ̀yà ara wọn ni ó lè jẹ́ ohun ìkọ̀ṣẹ̀ fún ọkùnrin. Abímbọ́lá (2006:) sọ pé:

Funfun niyì eyín
Ẹ̀gùn gàgààgà niyì ọrùn
Ọmú ṣíkí, ṣìkì ṣíkí niyì obìnrin
A díá fÉjì Òdí
tí ń sunkún aláìlóbìnrin (o.i. 56)

Èrò yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú orin Yẹ̀kínì Àjàó tí ó kọ nípa obìnrin nínú àwo orin rẹ̀ tí ó pe àkọlé rẹ̀ ní “Mo gbépo lọ́wọ̀” níbi tí ó ti kọ orin nípa obìnrin gẹ́gẹ́ bí afínjú àti ológe.

Lílé: Wúndíá bí ọlọ́mọge òbèlè sán ún
Lílé: Abilékọ bí ọlọ́mọge
Ègbè: Òbèlè sán ún
Lílé: Kò so tòbí mọ́, kò so yẹ̀rì mọ́
Ègbè: Òbèlè sán ún
Lílé: Kọjú sí mi, kẹ̀gbẹ́ sí mi, gbánú mọ́ mi, fẹ̀dọ̀ mọ́ mi, tìtìpámi mú, òló mi
Ègbè: Òbèlè sán ún

Yẹ̀kínì Àjàó fi obìnrin hàn gẹ́gẹ́ bí afínjú àti ológe tí ìmúra wọn máa ń fani mọ́ra. Obìnrin máa ń fẹ́ kí ìmúra wọn máa mú orí akọ wú kí ó sì le è fà wọ́n mọ́ra. Èrò yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Yorùbá pé kò sí obìnrin tí ó fẹ́ kí òun dàgbà lójú ọkọ rẹ̀. Ní





gbogbo ìgbà ni wọ́n máa ń fẹ́ kí ìmúra wọn fa ọkùnrin mọ́ra kí ó má baà wo obìnrin míràn.

**Obìnrin gẹ́gẹ́ bí Òjòwú**

Yẹ̀kínì Àjàó kò rólé apá kan fìkan sílẹ̀ nípa obìnrin. Bí ó ti rí ìwà tí ó dára nípa obìnrin bẹ́ẹ̀ náà ni ó tọ́ka sí àléébù wọn nínú àwọn orin rẹ̀. Àpẹẹrẹ mìíràn nípa àwòrán obìnrin tí ọ̀kọrin yìí fi hàn wá nínú orin rẹ̀ tí ó pè ní “Òjòwú Obìnrin”.

Òjòwú obìnrin
Bọ́ ọ bá ni o jẹun yóò jẹun
Bọ ọ bá ní ó mu yóò mu
Ṣùgbọ́n to bá ní ó mú kàìnkàìn
Kó lọ rè é wẹ̀ yóò wá bú ẹ̀kún
Olòṣì bí ti ń bú bàbá ọkọ
bẹ́ẹ̀ ní ń bú’yá ọkọ
Ẹnu òjòwú làwa ti ń mọbẹ̀ tó sè
Tó bá mú ewédú
Á fi bọ́jú á fi bọ́nu
bọ́ṣọ ń wọ̀wọ̀ tán a ni
Baálẹ̀ wọn ò ní gbọ̀fẹ́
Mo tún gbórin dé
Orin òjòwú‘bìnrin

Bí a bá wo àyọlò òkè yìí dáadáa, Yẹ̀kínì Àjàó ṣe àfihàn obìnrin gẹ́gẹ́ bí òjòwú tí ara wọn máa ń gbóná. Yàtọ̀ sí èyí, ọ̀kọrin yìí tún ṣe àfihàn òjòwúbìnrin gẹ́gẹ́ bí oníjà àti onílara. Bí ó ti ń bú bàbá ọkọ ni yóò máa bú ìyá ọkọ. Àjàó tún ṣe àfihàn òjòwú’bìnrin gẹ́gẹ́ bí ọ̀bùn tí kì í wẹ̀. Ó ní ẹnu òjòwú lati ń mọ ọbẹ̀ tí ó sè. Tí a bá wo èrò Yẹ̀kínì Àjàó nípa èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá nípa obìnrin, a ó ri pé ó bá èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá mu nípa pé wọ́n jẹ́

onílara àti pé wọ́n máa ń ṣẹ̀ẹ̀kẹ́ èébú. Ṣùgbọ́n ó ṣe é ṣe kí obìnrin jẹ́ òjòwú kí ó má ya ọ̀bùn gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú orin rẹ̀. Torí náà, èrò rẹ̀ pé òjòwúbìnrin jẹ́ ọ̀bùn kò fi gbogbo ara bá èrò Yorùbá mu nípa òjòwúbìnrin.

## Obìnrin gẹ́gẹ́ bí Alágbèrè àti Oníṣekúṣe

Lára ìwà tí kò bójú mu tí Yẹ̀kínì Àjàó tọ́ka sí nínú orin rẹ̀ ni ìwà àgbèrè ṣíṣe tí ó wọ́pọ̀ láàrin àwọn obìnrin. Àìlè mára dúró àwọn obìnrin kan ti sọ wọ́n di ẹṣin tí onínúurú ọkùnrin lè máa mú gùn bí ó bá ṣe wù wọ́n, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn obìnrin ni ó ń gbé oyún àlè fọ́kọ. Irú àwọn obìnrin yìí kò fi àpẹẹrẹ rere lélẹ̀ rárá. Àpẹẹrẹ orin tí Yẹ̀kínì Àjàó kọ fara hàn nínú àwo rẹ̀ tó pè ní "Mo gbépo lọ́wọ́" tí ó sọ pé:

> Tibi onílé san díẹ̀ ju tàjèjì lọ
> Tibi onílé san díẹ̀ ju tàjèjì lọ
> Ṣọ̀kí onílé, ṣọ̀kí àlejọ̀
> Ọkọ ló ń gboyún àlè pégba
> Tọ bá lọ̀ ọ́ bímọ tí ò gbédè
> O jẹyán kangbá
> Àbíró̩ ni? Kiní onílé san díẹ̀ ju tàjèjì lọ

Àyọlò òkè yìí ń ṣàpèjúwe obìnrin oníṣekúṣe aláìmọra, kòkọ̀kan àti àǹfààní àdúgbò. Abilékọ obìnrin tí ó lọ́kọ sílé tí ó tún ń yan àlè níta. Èrò Yorùbá nípa àwùjọ ni pé akọ ni ó lorí. Bí ọkùnrin tilẹ̀ ń yan àlè tí gbogbo ayé ń ri, kò tọ́ sí obìnrin. Síbẹ̀ a rí àwọn obìnrin tí wọ́n ń yan àlè ní ìkọ̀kọ̀ tí wọ́n sì ń gbé oyún àlè fọ́kọ. A lè sọ pé èyí rí bẹ́ẹ̀ nítòótọ́ ní ayé àtijọ́ torí pé aláya beẹrẹ ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọkùnrin. Wọn kì í lè tẹ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìyàwó wọn lọ́rùn nípa ìbálòpọ̀, èyí sì lè fà á kí irú àwọn obìnrin bẹ́ẹ̀ máa na ẹsẹ̀ síta fún ìbálòpọ̀ láti tẹ́ ara wọn lọ́rùn. Bákan náà, bí a bá fi ojú Karl Marx (1848) wo ìwà àgbèrè tí Yẹ̀kínì Àjàó kọrin pé àwọn obìnrin kan ń hù yìí, a lè sọ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn ni ó





Ondo Journal of Arts, Faculty of Arts, Adeyemi Federal University of Education, Ondo. Vol. 2. No. 1&2, 2026 | Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀-Èrò Yorùbá àti Ìbáyému Nínú Àṣàyàn Orin Yẹ̀kínì Àjàó

gba àgbèrè gẹ́gẹ́ bí ìdókòwò tí ó ń mú owó wálé fún wọn, tí wọ́n sì ń ṣe é bí ẹni lọ sí ibi iṣẹ́ òòjọ́. Èyí túmọ̀ sí pé bí àwùjọ tilẹ̀ kọjú oro sí ìwà yìí, èrò ti wọn ni pé ọ̀nà àtijẹ àtimu àti ìdókòwò àwọn ni.

## Èrò Yorùbá Nípa Ikú

Yorùbá gbàgbọ́ pé ikú lòpin ẹ̀dá. Ò báà lóògùn tó àrọ̀nì, ikú lòpin ẹ̀dá. Ọjọ́ ikú kò gbóògùn. Àìmàsìkò tí ènìyàn yóò kú ló ń dààmú ẹ̀dá. Yẹ̀kínì Àjàó fi èyí hàn nínú orin rẹ̀ tí ó pè ní "Mo gbépo Lọ́wọ́" níbi tí ó ti ń kọ orin arò ṣe ìdárò ìyá Àwọ̀yè tí ó papòdà pé:

> Mo gbépo lọ́wọ́ mo ń tọ̀yá Àwọ̀yè lọ o
> Mo gbépo lọ́wọ́ mo ń tọ̀yá Àwọ̀yè lọ
> Ìyá wa kú
> A dárò dárò a sunkún sunkún
> Kò bẹ́kún lọ
> Mo gbépo lọ́wọ́ mo ń tọ̀yá Àwọ̀yè lọ

Bí Yẹ̀kínì Àjàó ṣe gbé èrò rẹ̀ kalẹ̀ nípa bí a ṣe ń dárò òkú àti bí a ṣe ń ṣe nígbà tí òkú bá kú ṣe wẹ́kú pẹ̀lú èrò àti àṣà Yorùbá nígbà tí òkú bá kú. Tí òkú bá kú ní ilẹ̀ Yorùbá, wọn kì í tẹ́ òkú sínú òkùnkùn lálẹ́. Epo tí wọ́n gbé lọ́wọ́ tí wọ́n fi ń tọ ìyá tí ó kú lọ ni epo tí wọ́n máa ń dà sí fìtílà elépo tí wọ́n máa ń gbé sí ibi tí wọ́n tẹ́ òkú sí láti má jẹ́ kí ó wà lókùnkùn. Ìpèdè "Kò bẹ́kún lọ" ní ìlà karùn-ún ń tọ́ka si pé àgbàlagbà ni ẹni tí ó kú, kì í ṣe òkú ọ̀fọ̀, nítorí ìdí èyí, òkú ẹ̀kọ ni, ìwọ̀nba ni ó sì yẹ kí ẹkún sísun mọ gẹ́gẹ́ bí èrò àti ìgbàgbọ́ Yorùbá.

Ondo Journal of Arts, Faculty of Arts, Adeyemi Federal University of Education, Ondo. Vol. 2. No. 1&2, 2026 | Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀-Èrò Yorùbá àti Ìbáyému Nínú Àṣàyàn Orin Yẹ̀kínì Àjàó

## Èrò Yorùbá Nípa Elédùmarè

Yorùbá gbàgbọ́ pé Olódùmarè ló dá ohun gbogbo. Òun ni Alámọ̀ tó mọ orí ẹ̀dá. Gbogbo ohun tí ó wà láyé, èyí tí ó ń mí àti èyí tí kò mí, iṣẹ́ ọwọ́ Olódùmarè ni. Ifá pe Olódùmarè ní Àkọ́dá, Aṣẹ̀dá. Ifá ní Olódùmarè nìkan ló tó gbójúlé. Bóyá la ṣe lè rí ọ̀kọrin kan tí yóò kọrin tí kò ní sọ̀rọ̀ nípa Olódùmarè. Èrò Yorùbá nípa Olódùmarè fara hàn nínú orin Yẹ̀kínì Àjàó tí ó pe àkọlé rẹ̀ ní "Mo gbépo lọ́wọ́".

Àgàn dákun mọ́mọ̀ bọkàn jẹ́ o
TorỌ́lọ́un ní í fún ni lọ́mọ
Ẹ̀dá ò sùn kó bọ́mọ nígbèrí ẹ̀
Òyìnbó tí ń ṣowó ò le è ṣọmọ
Àyàfi bí ó bá dá asọ̀rọ̀-mágbèsì

Bí a bá wo àyọlò orin òkè yìí, a ó ri pé ọ̀kọrin yìí ń fi Olódùmarè hàn pé Òun nìkan ló lè ṣọmọ. Kò sí ẹ̀dá alàáyè tí ó lè jí kó dédé bá ọmọ rẹ̀ ní ìgbèrí rẹ̀. Òyìnbó ti gbìyànjú títí láti ṣe ọmọ ṣùgbọ́n wọn kò rí ẹ̀mí ṣe. Oríṣiríṣi àwòrán ni wọ́n ti ṣe kódà wọ́n tún ṣe èyí tí à ń pè ní róbọ́ọ̀tì ṣùgbọ́n wọn kò rí èyí tí ó ń sọ̀rọ̀ ṣe. Èyí sì wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Yorùbá pé Olódùmarè nìkan ni Adẹ́dàá àti Aṣẹ̀dá, tí ó sì ní agbára láti fi ọmọ jíǹkí ẹnikẹ́ni tí ó bá fẹ́.

## Èrò Yorùbá Nípa Ọ̀rẹ́

Nínú odù Èjìogbè nínú ẹsẹ kẹta ni Abímbọ́lá (2014:15) ti ṣe àfihàn ọ̀rẹ́ pé:

Ọ̀rẹ́ ò gbẹlẹ̀ta
Elẹ̀jì lọ̀rẹ́ gbà
A díá fún sóoróyè ọmọ aṣaworoko…

Àyọlò òkè yìí ń ṣe àtìlẹyìn fún èrò Yorùbá pé èjì lọ̀rẹ́ dùn mọ. Yẹ̀kínì Àjàó gbé èrò rẹ̀ kalẹ̀ nípa ọ̀rẹ́ gẹ́gẹ́ bí ọ̀dàlẹ̀ àti asọ̀rọ̀-ẹni-lẹ́yìn. Yorùbá bọ̀ wọ́n ní ọ̀rẹ́ ní í la ni ọ̀rẹ́ ní í pa ni. Yorùbá gbà pé oríṣiríṣi ọ̀rẹ́ ló wà. A ní ọ̀rẹ́ òtítọ́, bẹ́ẹ̀ ni èyí tó lè ṣekúpani ló pọ̀ jù. Èrò yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Yorùbá pé ọ̀dàlẹ̀ ọ̀rẹ́ àti asọ̀rọ̀-ẹni-lẹ́yìn wà. Èyí fara hàn nínú àwo orin rẹ̀ tí ó pe àkọlé rẹ̀ ní "Ẹ gbọ́ nàsíà mi" pé:

Àwọn tí wọ́n ń ṣọ̀rẹ́ ọkọ;
ni wọ́n tún ń ṣọ̀rẹ́ àlè
Àwọn náà ṣá ló ń gbowó;
alárinà tó bá jáṣẹ́
Ibi tí wọ́n tẹ́ní ọkọ sí ni wọ́n tẹ́ tàlè sí

Irú ọ̀rẹ́ tí ọ̀kọrin yìí ń tọ́ka sí nínú àyọlò òkè yìí jẹ́ ọ̀dàlẹ̀ ọ̀rẹ́ tí ó ń ṣe tọ̀tún tòsì tí ó sì ń ba ibẹ̀ jẹ́.

Bákan náà ni ó tún ṣe àpèjúwe ọ̀rẹ́ ọ̀dàlẹ̀ nínú àwo orin rẹ̀ tí ó pè ní "Ògún Baálẹ̀ Mọ̀so" níbi tí ó ti kọrin báyìí pé:

Lílé: Ìgbésí ayé mi
Ègbè: Kò ní lè jọ taṣebi
Lílé: Ìgbésí ayé mi
Ègbè: Kò ní lè jọ taṣebi
Lílé: Ọ̀dàlẹ̀ ọ̀rẹ́
Ègbè: E è é e e
Lílé: A pẹ̀yìndà tán lẹ̀ ń sọ̀rọ̀ lẹ́yìn

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní ṣàṣà ènìyàn ní í fẹ́ ni lẹ́yìn, tajá tẹran ní í fẹ́ ni lójú ẹni. Ọ̀dàlẹ̀ ọ̀rẹ́ ló pọ̀ jù ní àwùjọ wa. A fẹ́ ká jẹ má jẹ kí á yó. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀rẹ́ ló máa ń feyín sí ni lójú ẹni ṣùgbọ́n tí ó jẹ́ pé ata ni wọ́n fi sẹ́nu lẹ́yìn. Irú èyí ni Àjàó ń ṣe àfihàn nínú orin rẹ̀. Èrò yìí sì bá èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá mu rẹ́gí.

Lára àpẹẹrẹ mìíràn tí a tún bá pàdé nínú orin Yẹ̀kínì Àjàó nípa ọ̀rẹ́ nínú àwo rẹ̀ tí ó pè ní "Nǹkan're lọkọ" ni a ti rí àyọlò orin yìí:

Òpó à bá fẹ̀yìntì,
Ṣùgbọ́n wọ́n ti mẹ́fun dẹ̀gbẹ́ o
Ènìyàn tá à bá finú hàn
ní í jáláròkiri ẹni
Àwọn inúnibíni kàràǹbàní
ó sàní àbẹ̀kẹ́ jéńgbé

Bákan náà ni a ri fàyọ nínú àyọlò òkè yìí pé ènìyàn ṣòroó gbára lé. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, àwọn tí à ń finú hàn lè jẹ́ ọ̀rẹ́ tímọ́tímọ́ tàbí ẹbí ẹni. Irú àwọn ènìyàn báyìí tí a sábà máa ń gbára lé ló máa ń rojọ́ ẹni kiri tàbí ṣekú pani láìmọ̀. Èrò yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá tí ó sọ pé bánúsọ má bénìyàn sọ. Ẹni a ní kó fẹ́ni lójú, ata ló fi sẹ́nu, ẹni à bá fẹ̀yìn tì ló tún jẹ́ aláròkiri ẹni.

**Ọ̀rẹ́ gẹ́gẹ́ bí Aláṣìírí**

Yẹ̀kínì Àjàó gbé èrò ọ̀rẹ́ rẹ̀ kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹni tó lè daṣọ àṣírí bo ni ní ìgbà ìṣòro. Ìṣòro bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ ti owó tàbí nípa àdúrótì ní ìgbà ìbánikẹ́dùn. A rí èyí nínú orin rẹ̀ tó pe àkọlé rẹ̀ ní "Àlàfo Àṣírí" tó sọ pé:

Aláṣọ àṣírí Àkànó ò
Aláṣọ àṣíri
Bàṣiri rẹ, báṣirí rẹ bá bò bo tèmi
Aláṣọ àṣírí

Èrò yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Yorùbá. Ẹni tí Yorùbá bá ti ń yá owó lọ́wọ́ rẹ̀ ni wọ́n ń pè ní ọ̀rẹ́ minú tàbí aláṣírí. Ọ̀rẹ́ a máa yá ni lówó tàbí ohun èlò mìíràn láti lè bo àṣírí ọ̀rẹ́ rẹ̀.

**Èrò Yorùbá Nípa Ahun**

Ahun ni ènìyàn tó háwọ́ tí àti fi fún ni máa ń di ogun fún. Ibi tí gbogbo ẹgbẹ́ ahun bá ti ń náwó, ìráhùn ló máa ń ná. Yorùbá gbàgbọ́ pé ahun kò ráyé wá ṣùgbọ́n òkè lọwọ́ afúnni ń gbé. Nínú àwo orin Yẹ̀kínì Àjàó, ó ṣe àpèjúwe ahun nínú àwo orin rẹ̀ tí ó pè ní "Nǹkan rẹ ló kọ". Nínú àwo orin rẹ̀ ni ó ti ṣe àpèjúwe ahun báyìí:



Ondo Journal of Arts, Faculty of Arts, Adeyemi Federal University of Education, Ondo. Vol. 2. No. 1&2, 2026 | Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀-Èrò Yorùbá àti Ìbáyému Nínú Àṣàyàn Orin Yẹ̀kínì Àjàó

Àwá mọlé ahun a à ń dọ́dọ̀ ahun
Ènìyàn ò ní rí wa lọ́dọ̀ kàtá ká dúró
Ọmọ àlè lahun, olòṣì lahun
Tó bá ti gbọ́lù yó họ ni
Á wá lọ ẹ̀yìnkùlé á wá máa tẹ́ẹ́ mùẹ̀ mùẹ̀
Á ní kiní wọn yìí dùn jọjọ ẹ jẹ́ a bá wọn jo
A rí wọn lọ́sán a mọ̀ wọ́n lóru
A mọṣẹ́ tí baba kálukú ń ṣe

Àlàyé rẹ̀ nípa ahun pé tí ó bá ti gbọ́ ìlù ni yóò feré ge túmọ̀ sí pé kò fẹ́ náwó fónílù. Ahun máa ń fara pamọ́ níbi tí ó bá ti yẹ kí ó náwó tàbí kó máa wí àwáwí. Yorùbá kò fi ojúure wo ẹni tó bá láhun. Wọ́n tiẹ̀ máa ń pa á lówe pé "a kì í láhun ká tún níyì". Wọ́n gbà pé ìwà ahun híhù kò dára.

**Àgbálọgbábọ̀**

Iṣẹ́ yìí ṣe àgbéyẹ̀wò èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá àti ìbáyému rẹ̀ nínú orin Yẹ̀kínì Àjàó. A ṣàlàyé ohun tí ewì jẹ́ torí ara ẹ̀ka ewì ni a ti rí orin kíkọ. A tún ṣe àlàyé ní ṣókí nípa Yẹ̀kínì Àjàó gẹ́gẹ́ bí olórin àtinúdá. A gbìyànjú láti wo díẹ̀ nínú èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá àti ìbáyému wọn pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àpẹẹrẹ nínú àṣàyàn orin tí Yẹ̀kínì Àjàó kọ. A lo tíọ̀rì ìfojú ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ wo lítíréṣọ̀ ṣe ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ náà. A ri nínú iṣẹ́ yìí pé èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá nípa obìnrin, ikú, Elédùmarè, ọ̀rẹ́, ahun ló sodo sínú àwọn orin àpàlà Ọ̀yọ́ rẹ̀. Láti lè gbé ìgbé-ayé ìrọ̀rùn àti àlàáfíà, a nílò láti máa fi èrò àwùjọ wa sọ́kàn nínú iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ gbogbo tí a bá ń ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀. Yẹ̀kínì Àjàó fi àwọn orin rẹ̀ pe àkíyèsí àwùjọ sí àwọn ohun ìjìnlẹ̀ tí wọn kì í ro àròjinlẹ̀ lé lórí. Èyí túmọ̀ sí pé ẹni ayé bá yé yóò fi gbogbo èrò wọ̀nyí sọ́kàn nínú gbogbo ohun tí ó bá ń ṣe kí ó lè kógo ayé já. Yẹ̀kínì Àjàó gẹ́gẹ́ bí olórin àpàlà ìbílẹ̀ ń gbìyànjú láti fi orin rẹ̀ tún àwùjọ ṣe kí àwùjọ lè dàgbà sókè.

*Ondo Journal of Arts, Faculty of Arts, Adeyemi Federal University of Education, Ondo. Vol. 2. No. 1&2, 2026* | Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀-Èrò Yorùbá àti Ìbáyému Nínú Àṣàyàn Orin Yẹ̀kínì Àjàó

## Ìwé Ìtọ́kasí

Abímbọ́lá, W. *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá Apá Kìn-ín-ní*. Ìbàdàn: University Press Plc. 2014.

Ajíbádé, G.O. àti Rájí, S.M. *Ewì Àlàbí Ògúndépò*. Ìbàdàn: Amazing Grace Computer. 2011.

Barber, K. "Sociology of Yorùbá Oríkì". Unpublished Ph.D. Thesis, University of Ife, Ilé-Ifẹ̀. 1979.

Marx, K. *The Community Manifestos*. Penguin Books. 1848.

Ọlátúnjí, O.O. *Ewì Adébáyọ̀ Fálétí*. Ìbàdàn: Heinemann Educational Books (Nig) Limited. 1982.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí, J.A. *Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lò-èdè*. Òṣogbo: Tanímẹ̀hìnọ̀la Press. 1997.

Taine, Hippolyte. Historic de la Littérature anglaise. 4vds, Librairie de L. Hochette et cie. 1863-1864.

Taine, H. *The Sociology of Literature*. London: Paladis Publication. 1977.

Wakepedia. *Poetry*. Retrieved from https://enwikipedia.org on 02/02/26. 2016.